LAGOS STATE GOVERNMENT
MINISTRY OF EDUCATION

UNIFIED SCHEMES OF WORK
## PRIMARY SCHOOLS

**ÈDÈ YORÙBÁ ÀGBÉYẸWÒ ÀTẸ ÈTÒ TITUN FÚN** **ỌLỌ́DÚN KẸFÀ (PRIMARY 6) *SA´A` KEJI`***

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒNGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYENI |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Ìdánwò Ránpẹ̀ fún ìbẹ̀rẹ̀ sáà tuntun | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>- mú gbogbo àwọn ẹ̀kọ́ tí wọ́n ti kọ́ ni sáà tí ó kọjá wá sí ìrántí. | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dáhùn àwọn ìbéère inú ìdánwò ránpẹ̀ fún ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ sáà tí ó kọjá. | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ dáhùn àwọn ìbéère inú ìdánwò ránpẹ̀ fún ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ sáà tí ó kọjá. | Ìmọ̀ àtẹ̀yìnwá àti àwọn àkọsílẹ̀ àtẹ̀yìnwá |
| 2 | Ède:Itẹsiwaju Ẹkọ ninú òǹkà Yorùbá 200 – 250 (igba - ọ̀tàlúgba-dín-mewàá)/Àádọ́ta-lé-lúgba | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Ka òǹkà Yorùbá ní nọmba àti ní èdè Yorùbá<br>-kọ òǹkà Yorùbá ní nọmba àti ní èdè Yorùbá<br>-Ṣe àròpọ̀,ìyọkúrò àti ìsọdipúpọ̀ ní ìlànà èdè Yorùbá<br>- dáhùn ìbéère lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ka òǹkà tó wà lára sáàtì ní èdè Yorùbá lọ́kọ̀ọ̀kan.<br>-ka òǹkà láti igba dé Àádọ́ta lé lúgba.<br>-Ṣe àròpọ̀, ìyọkúrò àti ìsọdipúpọ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ<br>-pínra sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti ṣe àṣepọ̀ iṣẹ́ lórí kókó ìdánilẹ́kọ̀ọ́<br>-Kọ ohùn tí kókó iṣẹ́ dá lé lórí sínú ìwé wọn.<br>- dáhùn ìbéère lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀ | Ìdì igi ìṣáná àti kóró àgbálùmọ̀.<br>Sáàtì tí a kọ òǹkà èdè Yorùbá sí.<br>https://sites.google.com/site/learnyorubafree/yoruba-counting---onka-yo/counting-onka-yoruba |
| | Àṣà:<br>Ìgbéyàwó nílẹ̀ Yorùbá. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Ṣàlàyé kí ni àṣà ìgbéyàwó?<br>-Dárúkọ oríṣiríṣii ìgbéyàwó tó wà àti bí a ṣe ń ṣewọ́n.<br>-ìlànà àti ìgbésẹ̀ inú | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àṣà ìgbéyàwó ní ilẹ̀ Yorùbá.<br>-Olùkọ́ pín àwọn akẹkọọ sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ lati ṣe àṣepọ̀ iṣẹ́-<br>Ọ̀wọ́ kọọkan jíròrò | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀ | Àwòrán ayẹyẹ ìgbéyàwó abínibí àti àwọn ohun èlò ìdána.<br>https://edudelighttutors.com/2020/05/09/asa-igbeyawo-ni-ile-yoruba/ |

| ỌSẸ̀ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸ́YÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | àṣà ìgbéyàwó. Bí àpẹẹrẹ Ifojusade,ìwádìí, Alárìná, ìsìhùn,ìtọrọ ìdána abbl. Dárúkọ àwọn ohun èlò ìdána -Sàlàyé pàtàkì kí ọkọ gba ìpálé ìyàwó rẹ. - dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | lórí ohun èlò lèlána àti bí a ṣe ń fiwọ́n sadúrà. -Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àkọsílẹ̀ kókó iṣẹ́ sínú ìwé wọn láti ojú pátákó. iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ẹ̀kọ́ Ẹ̀rọ Ayélujára Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́ Ẹ̀kọ́ Ajẹ́máwùjọ | |
| | Lítíréṣọ̀:Ìtàn àwọn Akọni ilẹ̀ Yorùbá. i.Ẹfúnṣetán Aníwúrà | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè: -Ṣàlàyé ta ni akọni? -Ṣàpèjúwé àwọn akọni wọ̀nyí. -Da iṣẹ́/nǹkan tí wọ́n ṣe tó sọ wọn di akọni. - dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́: -Ṣàpèjúwe irú àwọn ẹ̀dá tí wọn ń pè ní akọni. -Sọ nípa àwọn akọni wọ̀nyí-ìgbà tí a bí wọn ọmọ ìlú tí wọ́n ń ṣe, bí wọ́n ṣe bẹ̀rẹ̀ ìgbé ayé wọn. -Ṣe ẹ̀kún rẹ́rẹ́ iṣẹ́ ribiribi tí wọ́n ṣe tó sọ wọ́n di akọni - dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti Ìbánisọ̀rọ̀ Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́ | Àwòrán àwọn akọni wọ̀nyí https://www.youtube.com/watch?v=oCs3suR0uWs |
| 3 | Ède:Àròkọ Asàrìyànjiyàn. (ilé ìwé ìjọba dára ju ilé ìwé aladani lọ) | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè: -Kọ àròkọ̀ tó múná dóko lórí orí ọ̀rọ̀ ilé ìwe ìjọba dara ju ilé ìwé aladani lọ -Ṣàlàyé ìlànà tí a ṣe ń kọ̀ àròkọ asàrí yàn jiyàn. -Dá àwọn ori ọ̀rọ̀ tí a lè bá pàdé lábẹ́ ìreìfẹ̀ àròkọ yìí. - dáhùn ìbéèrè lórí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́: -Sí ọwọ̀ọ̀wọ́ láti jíròrò lórí kíkọ àròkọ yìí. -Ọmọ kọ̀ọ̀kan kọ èrò tóni irú àròkọ yìí sílẹ̀. -Mu èro wọnyíí lọ́kọ̀ọ̀kan lati kọ àròkọ -Olùkọ̀ se ìtọ́sọ́nà níbi tó yẹ -Olukọ bawọ lu ìwé wọn | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀ Ẹ̀kọ́ Ẹ̀rọ Ayélujára | Ìwé ìròyìn àtìgbàdégbà: Akéde Oòduà talbí Aláròyé. https://olukoni.blogspot.com/2018/03/itosona-aroko-alariyanjiyan.html |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢẸ | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYẸNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | ẹ̀kọ́ yìí | - dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | | |
| | Àṣà:<br><br>Ẹ̀kọ́ ilé ní ilẹ̀ Yorùbá | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Fún ẹ̀kọ́ ilẹ̀ ní oríkì tó kójú òsùn wọn.<br><br>-Dárúkọ orísirísi ẹ̀kọ́ ilé tówà<br><br>-Ṣàlàyé òkọ̀ọ̀kan àwọn ẹ̀kọ́ ilé wọ̀nyí.<br><br>-Dá ìdí tí Yorùbá ṣe ń kọ́ àwọn ọmọ ní ẹ̀kọ́ ilé mọ́.<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ohun tí ẹ̀kọ́ ilé jẹ́.<br><br>-Sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti jíròrò lórí orisìí ẹ̀kọ́ ilé tó wà nípa dídárúkọ wọn.ìlànà, ìtọ́jú ilé,ìtọ́jú oúnjẹ, ọ̀rọ̀ síso,aṣọ fífọ abbl.ọmọ kọ̀ọ̀kan jíròrò lórí okọ̀ọ̀kan àwọn ẹ̀kọ́ wọ̀nyí.<br><br>-Ṣàlàyé ìdí tí ẹ̀kọ́ ilé ṣe jẹ́ àwọn Yorùbá lógún nígbà tí olùkọ́ ń kọ àwọn kókó wọ̀nyí sí ojú pátákó<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú Ìṣòro<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti Ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ẹ̀kọ́ Ẹ̀rọ Ayélujára | Àwòrán òbí tó ń kọ́mọ ní ẹ̀kọ́-ilé.<br><br>https://web.facebook.com/186211951400241 5/posts/eko-ile-tabi-kiki-ni-awon-yoruba-maa-nse-ogo-pupo-ninu-eko-ile-ti-nwon-nfun-awon/1868954719985 561/?_rdc=1&_rdr |
| | Lítíréṣọ̀:<br><br>Àkànlò èdè àti ìtumọ̀ wọn. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Fún àkànlò èdè ní oríkì.<br><br>-Ṣe àkójọ àpẹẹrẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ wọn.<br><br>-Lo àwọn àkànlò-èdè wọ̀nyí ní gbólóhùn.<br><br>-Ṣàlàyé ìwúlò àkànlò èdè<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Ṣàlàyé kí ni àkànlò èdè nípa wíwá oríkì rẹ̀<br><br>Pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà olùkọ́.<br><br>-Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti wà ní ọ̀wọ̀ọ̀wọ́, ọ̀wọ́ kọ̀ọ̀kan ṣe àkójọ onírúnrú àpẹẹrẹ àkànlò èdè àti ìtumọ̀ wọn.<br><br>-Lo àwọn àkànlò èdè wọ̀nyí ní gbólóhùn.Olùkọ́ ṣe ìtọ́sọ́nà níbi tó - dáhùn ìbéèrè lórsí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti Ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Ṣáàtì tí a kọ orisìí àkànlò-èdè àti ìtumọ̀ wọn sí.<br><br>https://web.facebook.com/watch/?v=3021679994610366 |
| 4 | Èdè: | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Ṣe àkójọ àwọn ọ̀rọ̀ | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Olùkọ́ kọ orí ọ̀rọ̀ sí ojú pátákó pẹ̀lú | Ọgbọ́n Àtinúdá àti | Ṣáàtì tí a kọ ọ̀rọ̀ àti |



edudelighttutors.com

| ỌSẸ̀ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸ́YÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | Ọ̀rọ̀ àti ìdàkejì rẹ̀ | Yorùbá lọ̀kan-ò-jọ̀kan.<br>-Wá ìdàkejì sí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí<br>-Lo àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ní gbólóhùn kíkún.<br>-Ṣe àkọsílẹ̀ kókó ìdánilẹ́kọ̀ọ́ sínú ìwé wọn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ìfinimọ̀nà ààyè àti àpẹẹrẹ<br>- Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ pínra wọn sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti jíròrò lórí kókó ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa sísẹ àkójọ ọ̀rọ̀ àti ìdàkejì ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí wọn kó jọ.<br>-Olùkọ́ ń pe akẹ́kọ̀ọ́ lọ̀kọ̀ọ̀kan láti sọ ìdàkejì ọ̀rọ̀<br>-lo ọ̀kọ̀ọ̀kan ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ní gbólóhùn<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọ̀yẹ<br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́ | Ìdàkejì sí |
| | Àṣà:<br>Àkójọpọ̀ àwọn òwe ilẹ̀ Yorùbá | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:<br>-Ṣàlàyé kíni òwe jẹ́<br>-Dárúkọ ìsọ̀rí òwe<br>-Ṣe àkójọ oníruurú òwe<br>-Tọ́ka sí ìwúlò òwe – ìlò òwe – ìbáwí, ìmọ̀ràn, ìkìlọ̀, àlàyé abbl.<br>-Sọ ìyàtọ̀ láàrin òwe wọ̀nyí<br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ṣàlàyé kíni òwe jẹ́<br>-Dárúkọ ìsọ̀rí òwe<br>-Ṣe àkójọ oníruurú òwe<br>-Tọ́ka sí ìwúlò òwe – ìlò òwe – ìbáwí, ìmọ̀ràn, ìkìlọ̀, àlàyé abbl.<br>-Sọ ìyàtọ̀ láàrin òwe wọ̀nyí<br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Ọ̀yẹ<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹ́máwùjọ<br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́ | Ṣáàtì tí a kọ orísìí òwe ilẹ̀Yorùbá sí.<br>Asaatioweyorubablogspot.com<br>https://web.facebook.com/oweyoruba.net/?_rdc=1&_rdr |
| | Litirẹ́ṣọ̀:<br>Eré oníṣe | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-i. Fún eré oníṣe ní oríkì<br>-ii. Ya àwòrán eré oníṣe ṣókàn<br>-Ṣe eré oníse láàrin | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>i. Kí oríkì eré oníṣe<br>ii. Dárúkọ orísìí eré oníṣe tí wọ́n ti wò rí<br>iii.Ṣe eré oníse láàrin ara wọn lórí ìtàgé<br>iv. bèèrè ìbéèrè tó rú | Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀ | Ìwé lítírẹ́ṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí Ìjọba yàn<br>Fídíò àgbéléwò fáwọn akẹ́kọ̀ọ́. |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒNGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYẸNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | ara wọn lórí ìtàgé<br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | wọn lójú<br>v. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ẹ̀kọ́ Ajẹ́mọ́wùjọ | https://www.worldcat.org/title/litireso-apileko-yoruba-ifaara-si-ere-onise-yoruba/oclc/14480625 0 |
| 5 | Èdè:<br>Àmì ohùn nínú èdè Yorùbá | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>i.Dárúkọ àmì ohùn tó wà nínú èdè Yorùbá<br>ii. Ṣàlàyé ìwúlò àwọn àmì ohùn yìí<br>iii. Ṣàpèjúwe àwọn àmì tí a ń lò fún àmì ohùn kọ̀ọ̀kan<br>iv. fi àmì sí orí ọ̀rọ̀ Yorùbá<br>v. Ṣàlàyé pàtàkì àmì ohùn nínú èdè Yorùbá<br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>i.Dárúkọ orísìí àmì ohùn tó wà nínú èdè Yorùbá (do-re-mi)<br>do – ( ̀ ) àmì ohun ìsàlẹ̀<br>re – ( - ) àmì ohùn àárín<br>mi – ( ́ ) àmì ohùn òkè<br>ii. Pínra sí ọ̀wọ́ láti fi àmil tó yẹ sí orí àwọn ọ̀rọ̀ yìí: wá, gbà, gbá, bàbá, wọlé, abbl.<br>iii. Ṣàpèjúwe àwọn àmì tí a ń lò fún àmì ohùn kọ̀ọ̀kan nínú abala ìwé kíkà wọn<br>iv. fi àmì sí orí ọ̀rọ̀ Yorùbá<br>v. Ṣàlàyé pàtàkì àmì ohùn nínú èdè Yorùbá<br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti Ìbánisọ̀rọ̀<br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹ́mọ́wùjọ | Saati tí a kọ orinuuru àmì ohùn àti ìlò wọn sí.<br>https://www.bbc.com/yoruba/47947465 |
| 5 | Àṣà:<br>Orúkọ Àmútọ̀runwá | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>i.Ṣàlàyé kí ni orúkọ àmútọ̀runwá pẹ̀lú àpẹẹrẹ.<br>ii.Dárúkọ orísirísìí orúkọ àmútọ̀nrúnwá<br>iii.Ṣàlàyé òkọ̀ọ̀kan | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>i.Ṣàlàyé kí ni orúkọ àmútọ̀runwá pẹ̀lú àpẹẹrẹ.<br>ii.pínra sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti se àkójọ orúkọ àmútọ̀runwá. Àpẹẹrẹ - Òjó, Àìná, Ìgè, Olúgbódi, Dàda, Òní, | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti Ìbánisọ̀rọ̀ | Ṣáátì tí a kọ orúkọ àmútọ̀runwá pẹ̀lú ìtumọ̀ wọn sí.<br>https://oldnaija.com/2017/02/03/oruko-amutorunwa-pre- |

| ỌSẸ̀ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸ́YẸ́NI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | àwọn orúkọ wọ̀nyí<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àlàbá, abbl<br><br>-Sàlàyé ìdí tí wọ́n fi sọ ọmọ ní orúkọ wọ̀nyí i.e.<br><br>Ìgè - Ọmọ tó mú ese wáyé dípò orí<br><br>Àlàbá - Ọmọ tí a bí tẹ̀lé/lẹ́yìn Ìdòwú<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | destined-names-in-yorubaland/ |
| | Lítíréṣọ̀:<br><br>Ìwé Kíkà - Ọlọ́rọ̀ Geere / Wuuru<br><br>Àwọn àṣà tó súyọ nínú àṣàyàn ìwé tí ìjọba fọwọ́ sí | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Fa àwọn àṣà tó súyọ nínú ìwé náà yọ<br><br>-Ṣe èkúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwọn àṣà náà<br><br>-Ṣàlàyé kókó tí ìtàn náà dá lé lórí<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Sọ nípa òǹkọ̀wé<br><br>-Pínra sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti ka ìwé náà pẹ̀lú ìtọ́sọ́nà olùkọ́<br><br>-Fa àwọn àṣà tó súyọ nínú ìwé náà yọ<br><br>-Ṣe èkúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwọn àṣà náà<br><br>-Ṣàlàyé kókó tí ìtàn náà dá lé lórí<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí ìjọba yàn |
| 6 | Ọ̀rọ̀ àpọ́nlé nínú èdè Yorùbá | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-fún ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ní oríkì kíkún<br><br>-Ṣe àkójọ orísìí ọ̀rọ̀ àpọ́nlé nínú gbólóhùn èdè Yorùbá<br><br>-Ṣàlàyé iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ń ṣe nínú gbólóhùn<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-fún ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ní oríkì kíkún<br><br>-Ṣe àkójọ orísìí ọ̀rọ̀ àpọ́nlé nínú gbólóhùn èdè Yorùbá<br><br>-Ṣàlàyé iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ń ṣe nínú gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ: ọ̀rọ̀ àpọ́nlé ń fi kún ìtumọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe<br><br>Àpẹẹrẹ - Adé sùn <u>fonfon</u><br><br>Bọ́lá sáré <u>tete</u> | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br><br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br><br>Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | Ṣáàtì tí a kọ ọ̀rọ̀ àpọ́nlé sí tí a fa ìlà sí lábẹ́.<br><br>https://www.youtube.com/watch?v=LJhsvB3bnVA |

edudelighttutors.com

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYẸNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | | Ó wẹ <u>tónítóní</u><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | | |
| | Àṣà<br><br>Iṣẹ́ abínibí ní ilẹ̀ wa | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>Ṣàlàyé àwọn ìsọ̀rí iṣẹ́ abínibí ní ilẹ̀ Yorùbá<br><br>-Dárúkọ àwọn iṣẹ́ abínibí ilẹ̀ Yorùbá<br><br>-Júwe bí a se ń ṣe àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí<br><br>Jírọ̀rò nípa àwọn ohun èlò iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Dárúkọ àwọn iṣẹ́ abínibí ilè Yorùbá<br><br>-Júwe bí a se ń ṣe àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí<br><br>-Jíròrò nípa àwọn ohun èlò iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br><br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br><br>Ìfọwọ́ṣowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | Àwòrán àwọn iṣẹ́ abínibí ilè Yorùbá àti àwọn ohun èlò iṣẹ́ náà.<br><br>https://web.facebook.com/145228489410874/posts/awon-ise-isenbaye-tabi-ise-abalayeawon-ise-abalaye-nile-yoruba-ni-wonyi1-agbegil/308680519732336/?_rdc=1&_rdr |
| | Lítíréṣọ̀<br><br>Fífa ẹwà èdè inú ìwé kíkà yọ | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-fún ẹwà èdè / ọnà èdè ní oríkì kíkún<br><br>- Fífi àwọn ẹwà èdè wọ̀nyí yọ àti ìtunmọ̀. Àpẹẹrẹ - Òwe, àwítúnwí, àkànlò-èdè, àfiwé, ìfohunpènìyàn<br><br>-Àlàyé kíkún lórí àwọn ẹwà èdè wọ̀nyí<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-fún ẹwà èdè / ọnà èdè ní oríkì kíkún<br><br>- Fífi àwọn ẹwà èdè wọ̀nyí yọ àti ìtunmọ̀. Àpẹẹrẹ - Òwe, àwítúnwí, àkànlò-èdè, àfiwé, ìfohunpènìyàn<br><br>-Àlàyé kíkún lórí àwọn ẹwà èdè wọ̀nyí<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br><br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br><br>Ìfọwọ́ṣowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | Ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí ìjọba yàn |
| 7 | **Ìdánwò Sáà Kejì**<br><br>**-Ìbẹ̀wò àwọn òbí**<br><br>**Ìsinmi ìdajì sáà keji** | **Ìdánwò Sáà Kejì**<br><br>**-Ìbẹ̀wò àwọn òbí**<br><br>**Ìsinmi ìdajì sáà keji** | **Ìdánwò Sáà Kejì**<br><br>**-Ìbẹ̀wò àwọn òbí**<br><br>**Ìsinmi ìdajì sáà keji** | **Ìdánwò Sáà Kejì**<br><br>**-Ìbẹ̀wò àwọn òbí**<br><br>**Ìsinmi ìdajì sáà keji** | **Ìdánwò Sáà Kejì**<br><br>**-Ìbẹ̀wò àwọn òbí**<br><br>**Ìsinmi ìdajì sáà keji** |
| 8 | | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè: | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>i.Kọ orí òrọ̀ | Ọgbọ́n Àtinúdá àti | Ṣáàtì tí a kọ ìlànà |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | Èdè:<br><br>Ìtẹ̀síwájú ẹ̀kọ́ lórí Àròkọ Aṣàríyàn jiyàn. | i.Kọ àròkọ tó bójú mu.<br><br>ii.Da àwọn orí ọ̀rọ̀ tí a lè bá padé lábẹ́ irúfẹ́ àròkọ yìí.<br><br>iii.Ṣe àmúlò àwọn ìlànà ìlapa èrò fún kíkọ àròkọ yìí<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | ìdanilẹ́kọ̀ọ sójú pátákó àti ìfàrà ṣíṣe láti ọ̀dọ̀ olùkọ́<br><br>ii.Ṣe àríyànjiyàn ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí ó sojú wa.<br><br>iii.Ṣe àpẹẹrẹ oríṣiríṣìí orí ọ̀rọ̀ tó jẹmọ́ àròkọ asàríyànjiyàn.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Òye<br><br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro | àròkọ aṣàríyànyàn sí.<br><br>https://www.youtube.com/watch?v=18f1affSprE |
| | Àṣà:<br><br>Ojúṣe òbí láwùjọ àti nínú ilé | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>i.Ṣàlàyé ta ni òbí?<br><br>ii.Mẹ́nu ba iṣẹ́ òbí lára ọmọ, láwùjọ àti láàrin ìlú.<br><br>iii.Bèèrè ìbéèrè lórí ohun tí kò yé wọn tó.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>i.Ṣàlàyé ẹni tí òbí jẹ́ lẹ́kùnrẹ́rẹ́.<br><br>ii.Dárúkọ iṣẹ́ tí òbí n ṣe lára ọmọ, nínú ilé àti laarin ilé<br><br>iii.Ṣe àkọsílẹ̀ kókó ìdanilẹ́kọ̀ọ.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹ́máwùjọ | Àwòrán àwọn òbí tó ń ṣe ojúṣe wọn láwùjọ. |
| | Lítíréṣọ̀:<br><br>Ìwé kíkà tí ìjọba fọwọ́ sí. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>i.Dá ka ìwé lítíréṣọ̀ yìí ní àkàgbádùn.<br><br>ii.Fún àwọn ọ̀rọ̀ ìtumọ̀ wọn farasin yọ.<br><br>iii.Ṣàlàyé ẹ̀kọ́ tí a ń kọ́.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>i.Ṣàlàyé ibi kíkà náà pẹ̀lú àtikún láti ọ̀dọ̀ olùkọ́.<br><br>ii.Ṣọ àwọn ẹ̀kọ́ tí a ń kọ́ nínú ibi kíkà yìí.<br><br>iii.Ayé fún akẹ́kọ̀ọ tó bá ní ìbéèrèèrè.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú Ìṣòro<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú Ìṣòro | Ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí ìjọba yàn<br><br>Káàdì pẹlẹbẹ tí a kọ ọ̀rọ̀ tuntun sí. |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒNGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | |
| 9 | Èdè:<br><br>Fífa ọrọ tuntun yọ nínú ìwé àkàyé àti itumọ wọn. | Ní òpin ìdánilẹkọọ, àwọn akẹkọọ yóò lè:<br><br>i.Ṣàkójọ àwọn ọ̀rọ̀ tuntun tó ṣuyọ<br><br>ii.Wá ìtumọ̀ sí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.<br><br>iii.Ṣe àmúlò wọn ní gbólóhùn kíkún.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹkọọ:<br><br>i.Pín ara wọn sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́, tí ọ̀wọ́ kọ̀ọ̀kan sì n ṣe àṣepọ̀ iṣẹ́ nípa kíka ìwé náà.<br><br>ii.Fa àwọn ọrọ titun náà yọ<br><br>iii. Pe àwọn ọ̀rọ̀ náà lọ́kọ̀ọ̀kan<br><br>iv. Ọ̀wọ́ kọ̀ọ̀kan lo ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ní gbólóhuln láti gbé ìtumọ̀ wọn jáde.<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọn Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọn Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣoro<br><br>Ọgbọn Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ọgbọn Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ̀ | Káàdì pélébé tí a kọ ọ̀rọ̀ tuntun sí. |
| | Àsà:<br><br>Ọ̀nà ìranra-ẹni-lọ́wọ́ | Ní òpin ìdánilẹkọọ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>i.Ṣàlàyé ọ̀nà ìgbaranra-eni-lọ́wọ́<br><br>ii.Dárúkọ àwọn ọ̀nà ìranra-ẹni-lọ́wọ́ nílẹ̀ Yorùbá<br><br>iii. Mẹ́nuba ìwúlò àti pàtàkì ìranraẹni-lọ́wọ́ láwùjọ<br><br>iv. dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹkọọ:<br><br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ọ̀nà ìranraẹni-lọ́wọ́<br><br>-Pínra sí ọ̀wọ̀ọ̀wọ́ láti ṣe àkójọ àwọn ọ̀nà ìranraẹni-lọ́wọ́. Àpẹẹrẹ ọ̀nà yíyẹ̀, iná mọ̀nàmọ́ná, omi ẹrọ, kíkọ ilé ìwòsàn ìgbàlódé. Bí àpẹẹrẹ: Àwọn ọ̀dọ́ ìlú máa ń yẹ̀nà, bẹ ọ̀wẹ̀, ààró.<br><br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọn Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọn Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣoro<br><br>Ọgbọn Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Àwòrán ọ̀nà ìranra-ẹni-lọ́wọ́ láwùjọ wa |
| | Lítíréṣọ̀:<br><br>Àwọn oúnjẹ abínibí ilẹ̀ Yorùbá | Ní òpin ìdánilẹkọọ, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-dárúkọ orísìí oúnjẹ ilẹ̀ wa<br><br>- Ṣàlàyé kíkún lórí bí a ti ń se oúnjẹ kọ̀ọ̀kan | Àwọn akẹkọọ:<br><br>-Dárúkọ orísìí oúnjẹ ilẹ̀ Yorùbá bí iṣu, iyán, àmàlà, gààrí, láfún, ẹ̀wà abbl.<br><br>-Ṣàlàyé bí a ti ń se | Ọgbọn Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọn Àrojinlẹ̀ àti | Ṣáálù tó ń ṣàfihàn àwọn oúnjẹ abínibí nílẹ̀ Yorùbá: Iyán Iṣu, èlùbọ́, ewéédú, ẹ̀gúsí, gbẹ̀gìrì, abbl |



edudelighttutors.com

| ỌSẸ̀ | ORÍ ỌRỌ̀ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌ́N ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸ́YÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | Ìṣu ẹ̀gbẹ, èlùbọ́, ewébẹ̀, abbl. | -jíròrò nípa ìwúlò / pàtàkì oúnjẹ<br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | oúnje kọ̀ọ̀kan<br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | yíyanjú ìṣòro<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | https://www.theyorubablog.com/ounje-yoruba/ |
| 10 | Èdè:<br>Gbólóhùn èdè Yorùbá.<br>-Gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ìṣe.<br>-Gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ ìṣe. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Fún gbólóhùn ní oríkì kíkún.<br>-Dá orísìrísìí gbólóhùn mọ̀.<br>Ṣàlàyé gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ìṣe àti ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ ìṣe. Pẹ̀lú àpẹẹrẹ.<br>-ṣàlàyé àbùdá àwọn gbólóhùn wọ̀nyí àti ìyàtọ̀ ààrin wọn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Dárúkọ orísìrísìí gbólóhùn tó wà.i.e gbólóhùn àbọ̀dé, ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ ìse, gbólóhùn ìbeere abbl.<br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ìṣe àti gbólóhùn ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ ìṣe.<br>-Ṣàlàyé àbùdá àwọn gbólóhùn wọ̀nyí àti ìyàtọ̀ tó wà láàrin wọn.<br>-Kọ kókó ìdánilẹ́kọ sínú ìwé wọn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br>Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | Àwòrán igi tó pẹ̀ka gbólóhùn<br>Ṣáàtì tí a kọ gbólóhùn ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀-ìṣe àti ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀-ìṣe.<br>https://edudelighttutors.com/2020/06/25/akole gbolohun/ |
| | Àṣà:<br>Ìṣẹ̀dá àti ìtànkálẹ̀ ọmọ Yorùbá. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Ṣàlàyé bí àwọn Yorùbá ṣe ṣẹ̀<br>-Mọ orírun wọn àti ìràn wọn ti ṣe.<br>-Mẹ́nuba bí wọ́n ṣe tàn kálẹ̀.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ṣàlàyé bí ìran Yorùbá ṣe ṣẹ̀. Ibo ni wọn tiṣe wá àti ohun tó ṣe okùnfà.<br>-Ṣàpèjúwe ẹ̀yà Yorùbá pẹ̀lú bí wọ́n ṣe tàn kálẹ̀.<br>-Ṣe àkọsílẹ̀ ohun tí kókó ìṣẹ dá lé lórí sínú ìwé wọn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br>Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | Àwòrán àwọn ìlú tí àwọn ọmọ Yorùbá tẹ̀dó sí |
| | Litireṣọ: | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́: | Ọgbọ́n wíwá ojútùú sí | Àwòrán ẹni tó ń ké |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒŃGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸ̀YÉNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | Ewì Àtinúdá. | àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Fún ewì ní oríkì kíkún.<br>-Ronú jinlẹ̀ láti kọ ewì.<br>-Mọ èròjà ewì<br>-Ṣàlàyé ìlànà ewì.<br>-Kéwì fúnra wọn.<br>-dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | -Fún ewì ní oríkì kíkún láti gbé àwòrán rẹ̀ sí ẹni tó ń gbọ lọ́kàn.<br>-Sọ àwọn èròjà ewì àpẹẹrẹ àwọn ọnaọ èdè, ìlà sí ìlà, ìlà púupùpú abbl.<br>-Ṣàlàyé ìlànà àkọsílẹ̀ ewì. Bí a ṣé ń kọọ́ ní ìlà sí ìlà.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | ìṣòro àti àròjinlẹ̀<br>Ọgbọ́n àtinúdá àti ìfojúsùn.<br>Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìbáraẹnisọ̀rọ̀ | ewì<br>Àwòrán akẹ́kọ̀ọ́ ọkùnrin/obìnrin tó ń kéwì. |
| 11 | Èdè:<br>Ọ̀rọ̀ Àpèjúwe | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Fún ọ̀rọ̀ àpèjúwe ní oríkì kíkún.<br>-Ṣàlàyé ọ̀rọ̀ àpèjúwe.<br>-Lo ọ̀rọ̀ àpèjúwe ni gbólóhùn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Fún ọ̀rọ̀ àpèjúwe ní oríkì láti gbé àwòrán rẹ̀ jáde.<br>-Fún ọ̀rọ̀ àpèjúwe yọ nínú gbólóhùn-fiofio,dudu pupa abbl.<br>-sọ̀rọ̀ lórí iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ àpèjúwe ń ṣe nínú gbólóhùn.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Saati tí a kọ àwọn ọ̀rọ̀ àpèjúwe sí.<br>https://olukoni.blogspot.com/2018/09/isori-oro-part-of-speech.html |
| | Àṣà:<br>Agbára èdè Yorùbá. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br>-Ṣàlàyé kíkún lórí agbára èdè Yorùbá<br>-Dárúkọ àwọn ohun tí à ń lo èdè Yorùbá fún. Àpẹẹrẹ-Àdúràgbígbà ìwúre,èébú bíbú àti èpè ṣíṣẹ́.<br>-Sọ̀rọ̀ lórí pàtàkì èdè láwùjọ.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí agbára èdè Yorùbá.<br>-Sọ̀rọ̀ lórí pàtàkì èdè Yorùbá: i.e ìbánisọ̀rọ̀, abbl.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àròjinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Àwòrán tó ń ṣàfihàn agbára èdè Yorùbá |


edudelighttutors.com

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒNGBÀ | AKITIYAN | ỌGBỌN ÀMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYẸNI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | ẹ̀kọ́ yìí | | | |
| | Lítírésọ̀.<br><br>Iṣẹ́ ṣíṣe (kí á má ṣe ìmẹ̀lẹ́). | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Ṣàlàyé pàtàkì iṣẹ́ ṣíṣe.<br><br>-Mẹ́nu ba ìhà tí Yorùbá kọ sí ìmẹ̀lẹ́.<br><br>-Ṣàlàyé àtubọ̀tán iṣẹ́ ṣíṣe àti ìmẹ̀lẹ́ ṣíṣe<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Ṣàlàyé àǹfààní tàbí ìwúlò iṣẹ́ ṣíṣe.<br><br>-Ṣàlàyé ìhà tí Yorùbá kọ sí ìmẹ̀lẹ́ ṣíṣe –ojú burúkú ni Yorùbá fi ń wo ọ̀lẹ.<br><br>-Mú ìwé wọn jáde láti kọ àkọsílẹ̀ kókó ẹ̀kọ́. | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Ìwé lítírésọ̀ àpilẹ̀kọ tí ìjọba yàn |
| 12 | Èdè:<br><br>Ẹyán ọ̀rọ̀ nínú gbólóhùn. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Fún ọ̀rọ̀ ẹ̀yán ní oríkì kíkán.<br><br>-Ṣàpèjúwe ọ̀rọ̀ ẹ̀yán.<br><br>-Fàlà sí ọ̀rọ̀ ẹ̀yán nínú gbólóhùn.<br><br>-Mọ iṣẹ́ tí ọ̀rọ̀ n ṣe nínu gbólóhùn.<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Fún ọ̀rọ̀ ẹ̀yán ní oríkì láti gbé àwòrán rẹ̀ síra wọn lọ́kàn.<br><br>-Ṣe àpèjúwe ọ̀rọ̀ ẹ̀yán nínu gbólóhùn.i.e<br><br>Tọla ra bàtà pupa<br><br>Aṣọ dúdú ọ̀jọ́ wọ̀.<br><br>-Ṣàlà sí ọ̀rọ̀ ẹ̀yán lábẹ̀ nínú gbólóhùn.<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀<br><br>Ọgbọ́n Ìdarí Akẹ́kọ̀ọ́<br><br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Sáàtì tí a kọ oníruuru ọ̀rọ̀ ẹ̀yán sí.<br><br>https://olukoni.blogspot.com/2018/03/eyan-oro-ninu-gbolohun.html |
| | Àṣà:<br><br>Àǹfààní àti àlébù iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:<br><br>-Ṣàlàyé ohun tí iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe jẹ́.<br><br>- Dárúkọ orísìírísìí iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe láàrin Yorùbá.<br><br>-Ṣàlàyé àǹfààní tó wà nínu iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe. | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br><br>-Ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe jẹ́ pẹ̀lú àpẹẹrẹ.<br><br>-Ṣàlàyé àǹfààní tó wà nínú iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe.<br><br>-Kọ kókó ìdánilẹ́kọ sínú ìwé wọn.<br><br>- dáhùn ìbéèrè lórí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br><br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣòro<br><br>Ọgbọ́n Àjùmọ̀ṣe àti ìbánisọ̀rọ̀ | Ṣáàtì tí a ya orísìí iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe sí. |

| ỌSẸ | ORÍ ỌRỌ | ÈRÒNGBA | AKITIYAN | ỌGBỌN AMÚṢE | OHUN ÈLÒ AMÚṢẸYẸ́NI |
|---|---|---|---|---|---|
| | | -Dárúkọ àwọn àlébù iṣẹ́ ajùmọ̀ṣe.<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | ẹ̀kọ́ yìí | Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | |
| | Lítíréṣọ̀:<br>Kíka ìwé ìtàn àròsọ tí ìjọba yàn pẹ̀lú ẹ̀kọ́ tí à ń kọ́ nínú rẹ̀. | Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:<br>-Ka ìwé kíkà náà ní ẹ̀ka gbólóhùn.<br>-Ṣàpèjúwe àwòrán ẹ̀dá ìtàn.<br>-Ṣàlàyé kókó iṣẹ́ tí ònkọ̀wé ń sí àwùjọ waa.<br>-Ṣàlàyé àṣà Yorùbá tó ṣúyọ<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Àwọn akẹ́kọ̀ọ́:<br>-Ṣàlàyé kókó iṣẹ́ tí ònkọ̀wé ń sí àwùjọ waa.<br>- -Kọ kókó ìdánilẹ́kọ sínú ìwé wọn<br>- dáhùn ìbéèrè lórí ẹ̀kọ́ yìí | Ọgbọ́n Àtinúdá àti Òye<br>Ọgbọ́n Àrojinlẹ̀ àti yíyanjú ìṣoro<br>Ẹ̀kọ́ Ajẹmáwùjọ | Ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí ìjọba yàn |
| 13 | Àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ lórí iṣẹ́ṣáà yìí nínú Èdè, Àṣà àti lítíréṣọ̀ | Àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ lórí iṣẹ́ṣáà yìí nínú Èdè, Àṣà àti lítíréṣọ̀ | Àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ lórí iṣẹ́ṣáà yìí nínú Èdè, Àṣà àti lítíréṣọ̀ | Àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ lórí iṣẹ́ṣáà yìí nínú Èdè, Àṣà àti lítíréṣọ̀ | Àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́ lórí iṣẹ́ṣáà yìí nínú Èdè, Àṣà àti lítíréṣọ̀ |
| 14 | **Ìdánwò sáà kejì** | **Ìdánwò sáà kejì** | **Ìdánwò sáà kejì** | **Ìdánwò sáà kejì** | **Ìdánwò sáà kejì** |



edudelighttutors.com